**OWE YORUBA**

Awọ fẹrẹ bonu ko jẹki a rikun aṣeni. Ilẹ ti a fẹ akuko ko dẹna, ibi pipaje lo mọ. Ika ko fẹ ki a ru ẹru ki a sọ.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJO

**ASOJỌ ỌRỌ**

Igbin ka, ka, ka, ebiti ti ko gboju ko le pa igbin, Patako ẹfọn ka ka, lo uta aja l'ẹnu. Abata takete bi ẹni pe ko ba odo tan.

VOL. XII No. 661. LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 6. — FEBRUARY 12, 1960. KỌBỌ MEJI (2d)

# Kinla ! Ibosi Ole, Gbomo-gbomo De

Niwọn dede agogo mefa irole ọjọ Alamisi 4th osu Feb 1960 ni a gbọ ibosi o! ibosi ole ni opopo Docemo Street lagbegbe Idolawo, gbogbo awọn enia si sare lọ sibẹ, nwọn ri ọmọbinrin kan ninu moto ayokele ti awọn enia meji mu mọlẹ.

Nigbati ija wadi're wipe kinla iru obinrin yi ni nwọn fe gbe salo.

Nigbati awọn ọtelemuye tese bo oro na, nwon ni, oro ife lo da awon po. Sugbon oro yi si wa lowo awon olopa.

### YỌKOLU, IIYAWO GBỌKỌ ṢANLE ỌKỌ YỌKE

YABA Okunrin kan ti o nṣiṣẹ logba Reluwe wa sile lati jẹun ọsan nigbati o dele, o ba iyawo rẹ bori mọlẹ koiti ṣe onie. Inu bi i si eyi, sugbon o paa mora. Iyawo rẹ dapara wipe "Oku ko nsin ọba"

Ibe ni inu ti bi oko iyawo o bere si ko ese bo iyawo La tobe ti gbogbo awon aladugbo fi bere si lo s'ọkọ ati aya. Nwon mu iyawo lo sile keji. Ọko yi ko simi o fẹ lo ba iyawo re.

Ọpọ enia lo dimu ti nwon ko si jeki o ri aye lo ba iyawo re ja Oko na binu wole lo o jade sinu ogba o si fo ogba da si ile keji n i b i t i o nfi ibinu rin lo, o lo fi ese be igo. Nigbati eje npon bi omi ni nwon gbe lo sile alaisan. Nigbati ojade nile Alaisan won da okunrin yi duro lenu iṣẹ Ẹo ri, iya di meji bi a fi ada pa iru, ada se, iru salo.

### IKU DORO IKU ṢIKA IKU PA ALABI ARIYỌ

Iku mu Alakinkanju lọ! iku doro o mu Alabi kuro larin ẹbi! iku mu ọmọ pataki kuro larin ọrẹ! iku o ba gba owo a ba san! iku iku o ba gba ẹbọ a ba ra agbo! A bẹ iku titi iku o gbọ ẹbẹ! iku mu Sule lọ Sule ọrun rere! Ọrun rere!! Alabi Akuwa ọloko odo ọrun rere, ọrun rere. Awa Eleti - Ọfẹ ba awọn ẹbi ati ọrẹ ologbe Ariyọ kẹdun ki Olodumare fi si inu afẹfẹ rere.

### ITAN BI HAUSA TI ṢE DE ARIWA

(Lati Ọwọ B. A. Carew)

Gẹgẹbi Adehun wa wipe no sọ itan bi Hausa ti ṣe de ilẹ Ariwa, a ko fẹ ki enikẹni ṣi itan na gbọ nitoripe Hausa yatọ si Fulani.

Daju-daju ọpọlọpọ ninu ọkawe wa le ti mọ nipa itan yi, sugbọn eyi yio jẹ idunnu fun iru awọn bẹ ti ti wa yi ba ti wọn dọgba. Sibẹ-sibẹ, ako ni ṣe alai ri iyatọ diẹ ninu rẹ.

Bakanna ni itan yi yio jẹ anfani fun awọn ti nwọn ko ti mọ nipa rẹ rara.

Sibẹ-sibẹ, ako ni ṣe alaini ri iyatọ diẹ ninu rẹ. Bakanna pẹlu nipe yio tun jẹ anfani fun awọn ti nwọn koiti ka nipa rẹ rara.

Gbogbo wa mọ pe ko si odo kan ti ko ni orisun, beni ko si ẹgile-ede kan ti ko ni ẹniti o ṣe wọn.

Emu o jẹ Hausa jẹ ọkunrin agbara kan ti o ti de Baghdad wa, oruko re ni ma je Bayajida,

(Koti pari)

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branche Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, YABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Nathanaper London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

OVALTINE

Ntun Agbara Ati Okun Inu Se



## Awon Alabojuto Ero Meka



Eniti a nwo aworan yi ni Oloye S.L. Akintola tise Premier fun agbegbe Iwo-orun ile Nigeria, a i gbo wipe, o ti yan awon enia mefa kun awujo awon ti o ma alabojuto awon enia wa ni ileyi ti o nlo si Meka, gbogbo won di mokanla.

Oruko awon enia titun ti awon yan kun won na niwonyi, Alhaji S. Abiola, A.S. Adenumi, Shittu Basorun, J. Giwa, Y.A. Onasanya ati Amodu Momo

## Esin ni Olorun ni ki a wa se nile Aiye

Alufa Koranga Olorun oba so ninu iwe Mimo ti Alkurani wipe, ati enia ati Alijanu, on ko ran wa wasi ile aiye lati se ohun kan fun on Olorun bikose ki e ma sin on

Osa bi a o ti se ma sin Olorun na ni wipe ki a sin ni Lauro, ni ibere, ati ni ifordele, nitorina, eyi lo jeki esin Olorun di tulasi fun wa. Ohunkohun ti o wu ki o de si oluware tulasi ni ki o kirun fun Olorun

Bi iduro lo ba soro fun o na ti ko si jeki o sin Olorun, joko, ki o si sin Olorun lori ire. Bi ijoko ko ba si ro o lorun, eme dubule ki o si sin Olorun. Bi idubule ba si soro fun o fun na ika kan si oke, ki o si ma fi se apejuwe pe o nkirun. Bi eyi pelu ba je isoro fun o fi oju re se apejuwe pe nkirun, Nigbehin re patapata, bi iduro ko si si ibere ko si ti oko sile joko, bi o ba je wipe emi re si mbe laye, fi oka n kirun ki o si fi sin Olorun gegebi apejuwe pe o nkirun.



AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.



## The Nigerian Medicine Stores

"GBOMORO"

EGBOGI ATATA FUN IGBONA OMODE, IBA ORERE, INU-IWO ATI AIPERI.



IGBONA ATI ORISRISI ARUN MIRAN TI O MA NYO OMODE LENU NIGBA EHIN HIHU.

"GBOMORO"

Dara popo fun omo ikoko tabi Tunfulu. Kosemani ni egbogi fun eyin ehiyanmo. Ajebidan ni oruko re nje. Ko ni fa Jedijedi tabi igbe-orin fun omode. tete wa ra tire ni sobu wa :

THE NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU SQUARE, LAGOS

Tabi ni awon Eka wa ni :-

Port Harcourt, Jos, ati Ibadan.



## Owe Yoruba

Lati Owo Mosemiloluwa

1 Nwon ni aja ulojo ni awon se gbe aja ta ti nwon si fi ra obo, ise ki i obo nse?
2 A nwi iru, o nwi iru, iru ba se se obe ndan?
3 O nse Omo Oluku beni, won ko ni sin i mo ija re, bi o ti wu ki o ba yio sa re oko pena gari kan.
4 Bi ori Agbejoro ko ba pe, ori adajo ti yio da ejo na ti pe perepere.
5 Eniti o go, ko mase bina, eniti o gbon ni yio ko o. Aduni loro fi agbara koni.

EMA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

## AWON KURUMO FI ESIN OMI TA EISENHOWER LORE

LIBERIA. Ogbeni Eisenhower ti ise Baba egbe Alakoso ijoba ile Amerika ni a gbo wipe o lo be ile Liberia wo lati mo bi ilosiwaju ile na ti ri,

Nigbati o ma kuro nile na, awon fi omo esin-omi kekere kan ta lore wipe ki o mu lo si ile ibiti a gbe nse itoju awon eranko nile Amerika.

Ogbeni Eisenhower si fi ayo gba ebun na, o si ba oko ofurufu padu sile Amerika, Ijoba Kurumo lero lati gbe omo esin omi na sinu oko ofurufu lo si ile Amerika sugbon awon olorin ofurufu taku wipe, won ko le gba iru eranko be sinu oko oju Sanma, nitoripe bi o ba lo gbuja lakoko ti nwon mbe larin irin ise ati iku ki o ma ba wa je oni-ko fun won.

A si gbo wipe Ogbeni Eisenhower ti de ile lojo pipe sehin ki esin - Omi na to de oko oju omi de sile Amerika.

# Eniti O Nkose Gbagimole Nilu oyinbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni A. B. Kasunmu ti o jẹ okan ninu awon alejo ti o lo silu Oyinbo lo ko isẹ gbagimolẹ (Survey) ninu ile ẹko Cambridge University, Ọgbẹni Kasunmu jẹ okan ninu awon ti o lo ko isẹ yi lati agbegbe Iwo-Orun ilẹ Nigeria.

Awon ara ilẹ Amerika sọ pe ọrun keji yen nibiti a gbọ wipe Jerusalẹm titun wa nwọn jijọ ma gbe ibẹ ni Nwọn si ngbero pe awon o ti se kọ Hotel ati ile ibiti nwọn o ma gba epo sinu ọkọ ti o nlọ si ọrun keji si ofurufu.

Awọn Gẹsi ti de ọrun keji, sugbon nwọn kole bọ silẹ nitoripe nwọn mbẹ ni isorikodo si ara wọn a si gbọ pe ọpọ enia lo ti nfi oruko sile lati lo gbe orun keji Bo ba bajẹ gbogbo wa ni yio kan.

## AWON AGANYIN FẸ ŞE OFIN EWỌN ODUN GBORO F'OWO AIYEDERU

GHANA. Ijoba ilẹ Ghana ti ri oye wipe awọn enia fẹran Ọla oojọ, paapa awọn ọmọde kekeke ti nwọn sẹsẹ bẹrẹ igbesi aiye wọn nwọn a ma Kanju ati lowo kaka ki nwọn siṣẹ ooguṅ wọn ki nwọn si gba ibẹ ni owo lọwọ ọna bi nwọn o ti şe le şe aiye deru ki nwọn le di Manager jiji, ki nwọn kọ pẹtẹsi mẹfa papọ.

Awọn Igbimọ Aganyin sọ pe ko si owo ti nwọn le şe fun awọn enia ti o le mu wọn yọwọ kuro ninu jibiti, ayafi ki nwọn fata fun wọn. Nitori idi eyi nwọn fi şe ofin ewọn ati o majade lori re.

Bi Ọlọpa ba mu ẹnikan wipe o şe owo robi-robi [illegible] ẹwọn [illegible] kan [illegible] de, isẹ buruku [illegible] ma tun [illegible] Nitori eyi ẹnikẹni ti o ba tun dan iru ẹsẹ bẹ, nwọn ọdun gbere ti ko ni jade kuro ninu ẹwọn mọ ni wọn o ju si

## ORI GBA IYI LỌDỌ ẸLẸDA

Ninu gbogbo ẹda ti Ọlorun da sile aiye, ko si eyiti o mo iyi dida ti Ẹleda da on, sugbon nigbati Ọlorun se eda Ori ti o si mi emi re si, oro ti ori koko ma so ni mo dupe o, Ọba adeda.


Plushes, Velvet, Velveteens Damask & Building Materials

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street. (Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed


## Nibo Lao Gbe Bi Osupa Ba Ja Lule

Irohin ta siwa leti wipe awon enia aiye yi nwa orişiri ọna lati lọ gbe ọrun keji ile aiye ti awa yi ti su awọn ogunlọgọ enia nwọn fẹ lọ gbe ọrun laye gẹgẹbi Enoku, Elijah ati Jesu ti lọ, nitori pe ẹru iku mba wọn.

Nigbati nwọn sọrọ yi ọkunrin kan dahun wipe, Ọlọrun kuku şe e, nko niyawo, nko bimọ nko kọle nko l'oko nko l'odo boya bi mo ba de sanmọ keji ibẹ yio şe gbẹde fun mi.

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos. P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM "ELETI - OFE LAGOS" Phone 23370

VOL. XII. NO. 661. SATURDAY FEB. 6 - FEB. 12. 1960


## Ibinu Ko Da Nkan, Suru Baba Iwa

Suru ni baba iwa, agba ti o ba ni suru, ohun gbogbo l'oni : ti bi ni ọna keji ẹwẹ, "arin'rin gbẹrẹ ni yio m'oye dele, asare tete ko ni r'oye jẹ. Iwọnyi jẹ ede awọn Yoruba ti o nfi han awa ẹda ọmọ enia l'ode aiye yi wipe ohunkohun ti a ba dawọlẹ lati ṣe, ki a fi suru kun, k i a maṣe kanju rekọja tabi k i a maṣe fi wadu-wadu ṣe e, ki nkan na le bọsi rere.

"Ohun ti a f'ẹsọ mu ki ibajẹ, ohun ti a f'agbara mu ni o nini lara", ki enia to jẹ ẹni pataki l'ode aiye yi, o ni lati jẹ onisuru ti o ni ifarada ati iforiti pẹlu amu-mọra lai ko fi ibinu ṣe ohunkohun, nitoripe, bi enia ko ba ṣe ọmọ-iṣẹ, walai-talai kole ṣe ọga iṣẹ ki o rọgbọ.

A fi wosika wa ọsẹ yi ṣe ikilọ ati ẹkọ fun ẹnyin ọkawe wa wipe ko si ohun kan labẹ ọrun ti enia le ṣe laiko fi suru pẹlu rẹ ti nkan na le yọri si rere.

Suru l'ẹbọ!

## Akowe Agba Atijo Nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo'nu inu aworan yi ni Ọgbẹni Lennox Boyd, ẹniti o ti mbẹ ni ipo akọwe agba fun ile ajeji nilu Oyinbo, (Colonial Secretary) on ni ẹniti o ṣeleri Ominira fun ilẹ Nigeria pe ọjọ idande na yio jẹ ọjọ kini oṣu October 1960.






## Idajo Ejo Afojudi Ti Ogbeni Benson

Ogbẹni T.O.S. Benson, eni ti Ijọba mba ro ejọ wipe o se afojudi si adajọ kan ninu kotu nigbati o mbe lori ate idajọ re ni irohin tun kan wa wipe,

Ogbẹni Benson na mu ori bo ninu ejo na, sugbọn adajọ se ikilo fun u, o si wipe ki o ma lo ni alafia.

Awa Oniwe irohin Eleti-Ofe fi eyi ki Ogbẹni na wipe, o ku orire o ku ajaye. Ewu ina ko npa awodi Benson o ku ewu.


**Kere o!**

A ti ni oriṣiriṣi egbogi fun arun Inarun ati arun Jẹdi-jẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, l'ọkunrin ati l'obinrin. ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7. Egerton Road, Lagos

# Iyawo Adajo Agba Nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi, niwaju ode Afin Ọba ilu Oyinbo, ni iyawo Adajọ Agba (Lady Ademọla) ti ilẹ Nigeria nigbati o lọ gba iyi Oye M. B. E. ti Alaiyeluwa Ọba obinrin ilu Oyinbo fi da lọla lasiko ti nwọn lọ si Ipade ẹgbẹ Alanu (Red Cross Society) nilu ola London.

On ni a nwo ti o nfi "Ami-Oye" (Insignia) rẹ han iyawo Ọlọla Abayọmi (Lady Abayọmi) tilu Eko nile Nigeria.

## Okunrin ODe Ti O Fi Omo Ekun Ko Omo Re Jade

Daju-daju, b'o ti wa l'arin ẹda enia, bẹni o wa ninu ẹda ẹranko.

Nitori gbogbo wa l'a mọ gẹgẹ bi ọmọ ti ri lara obi, ko ba ṣe enia tabi ẹranko.

Bayi ni obinrin yi di iyawo ọde na, nwon si nba bo wa ti ko si ija tabi ita larin won obinrin yi fi suru joko pelu ọde na nitori ati gbesan.

Ẹyin ni ohun bi o ba bo sile ko ṣe ko mọ.

Li osan ijọ kan ti ọkunrin yi jẹun ti o yo tan, ti o mu omi tutu si i, ti ọkan rẹ balẹ, o bẹrẹ si ta kuro so pelu iyawo re titun, o nrẹrin, o ṣ i ndọkọkọ.

Iyawo re ni, „Bale wa, kini ṣayin ọde ima da nigbati ewu ba de si nyin ni aginju,?"

Ọde yidahun, o ni ‚awa ama da omi, okiti okuta, iro.'

Bi o ti pe iro ti ko ti pe e ja ni iya ọlọmọ ru ke e mo l'ẹnu pe.

‚Ọkunrin yi bi o ba yo tan, o ki dake isokuso,'? Bayi ni ọkunrin yi dake ọrọ sisọ ti ko si pe ọrọ na ja le mọ.

Ọjọ gori ojo osu, iyawo titun yi be ọkọ re pe, Iwo ọkọ mi mo fe da kan lo si ilu wa, mo si fẹ ki o ba mi lọ, ki o le mọ awon obi mi.

Inu ọkọ iyawo dun lati gbo bayi l'enu iyawo re, o si dahun pe, o dara, iyawo mi, aki ba ni rin, ki a ma mọ ile eni, emi yio lo pẹlu re.

(Koiti Pati)

### OLE IBADAN

Nigba aiye Akinwande Olori Ole Ibadan, ni alale awon ole a ma korin pe, ‚awọn ti yio ba ile yi je' ‚Balogun a si ma wipe n'Ibadan yi o, ao foju ole ri nkan.

## Popu Yio Ba Wa Yo Ayo Ominira

Nigbati Oloye F.S. Okotie-Ebo pada de silu' Eko ni ojo ọsẹ ọjọ kọnkanlelogbọn osu January, lati irin ajo ile Tangier Morocco, ti o ti lọ, o sọ wipe Ẹni-Mimọ Popu John Ketalelogun yio ran aṣo'u wa ba wa yọ ayọ ominira ile Nigeria ninu osu October.

O si tun sọ wipe Popu ni ki on so fun awon enia Nigeria wipe on yio se akanse adura fun alafia ati ire ile Nigeria ni ọjọ kini Osu October 1960.

E MA KA IWE

IROHIN

ELETI-OFE

LOSOSE

## JAMBA ṢELẸ SI AWON TI O NSIṢẸ NI AJA ILẸ

Ni ilu kan ti nwon npe ni Orange Free States, a gbo wipe iwon edogbeta enia dudu ati Oyinbo funfun mefa ni apata ya bo mọlẹ ti ko si ona ti a le gba fi gba emi won la. Fun odidi ojo kan pelu abo ọjọ ni awon ti o mbẹ ni oke ilẹ fi ṣe aapọn ati wahala ki a le gba won la ti o jẹ pabo ni gbogbo rẹ ja si.

Nigbati ireti gbogbo ti saki, ti o jẹ wipe apata ola kan ti o yi lati ori oke ibi ti awon nṣiṣẹ si iwọn edẹgbẹta ese wa sile lo se oniko iku awon enia na, awon ẹgbẹ Ologun Igbala (Salvation Army) duro lẹnu iho ti o se mo na, nwọn si ṣe isin ikẹhin fun awọn ti o ingbadi na.

Nibi isin ikẹhin na, awon enia dudu pe bi omi, awon ara, ebi, ibatan, iyawo ati awọn ti o jẹ ojulumọ fun awọn ti o ku sinu koto na gbogbo lo pejọpeṣẹ sibi isin na.

Ọkan ninu awọn enia ti o nṣe fita-fita lati gbẹ iho lọna miran titi lọ de ibiti awọn enia na wa sọ wipe, bi awon ba gbe de ibiti awọn enia na ku si nwọn osekan loni. Oloran fe be ni. Gbogbo awọn enia bi edẹgbeta na ni yio ti ku ninuripe ko si ona ti atẹgun le gba de ọdọ wọn mọ.

HINDU SANKARKE
Religious ...


## Olorun Maje Ki Eleru Kuro Ni Di Eru Re.

Gege bi itan wa yi mo ri daju pe oluka iwe, ir ... yi yio ri pe opolopo eko lowa ninu itan wa, yio si dara pupo ti a ba mu ninu re se Ogbon.

Agbo are yi ti kan biba ko omo obinrin na to de, nigbati o ye si won, gbogbo agbo da oju bo, awon ko si mo iru enia wo ni tabi ni bo ni o ti wa.

Gere ti omo oba fi oju kan, o ran okan ninu awon iranse re pe kio lo pe wa, omo na si joko ri egbe re etun. gbogbo enia ni won nwo omo na ni awo yi run.

Nigbati agbo are tuka, omo yi bo bata ese otun re sile gege bi ofin ti opolo fun o si pada lo ji yin fun opolo ti on duro de ni eti adagun omi ni ehinkunle won.

Opolo yi fa wo inu odo lo gege bi ti akoko o bo eso re re kuro o si ko awon akisa re pada fun, o tun fa gun oke pada omo obinrin yi pada lo si ile lati bere gbe ihgba wahala re.

Nigbati omo oba de ile o fi bata na han baba re o si wi fun pe, omo obinrin kan ni o wo wa bi are lana, o si gbagbe re.

Daju daju baba emi yio fe omo na, ngo si gbe ni iyawo.

Ni ojo keji, oba kede fun gbogbo ilu bayi „Enikeni ti bata odo ohun yi ba ba ni ese mu ni yio je iyawo omo oba"

Gbogbo ilu ati awon agbegbe bere si lo fi bata na di iwon ese won sugbon ko si eniti bata yi se dede ese re.

Omo orogun buruku yi na lo pelu, iya re wahala depo pe ki bata na je tire o fere le wipe ki a ke ese omo on si dede bata yi.

(Wo yoku loju ewe keje)

## ...I LO FA IKU AWON OMO WERE? O YE KA BERE WO.

Omode logbon, agba logbon, on li a fi da ile Ife, o ye ki a jijo peju bi ara wa lere wipe kini ohun ti o fa iku awon omo were?

Ohun ti a se akiyesi ni wipe ninu gbogbo awon omo ti a nbi lododun, idaji won lo nkabo ki nwon to pe omo odun kan. Idi oro na niyi o! kilofaa?

Apere kan niyi. Ni odun 1958, ati 1955, iye awon omo ti a bi nilu Eko, leni oke mejile-legbaa (42,596)sugbon nigbati awon ojogbon te istro bo o, nwon ri wipe, nigbati o ma fi di opin odun 1958, edegbejo (15,000) lo ti kabo ki nwon to pe omo odun kan.

Awon ojogbon ninu ise isegun wa dahun si oro na wipe, ohun ti o fa sababi iku awon omo weere nwonyi wa, ni awon obi eyi ni Iya ati Baba omode na ti o je alaimokan, ti e mo bi a ti nse aajo ati ojojo omo, ti nwon ko si ri eniti yio ko won tabi ti yio fi ona han won.

Imoran wa si enyin okawe wa ni wipe, bi omo nyin ba bimo, ki e ma se iranlowo fun lati ma ba se olojojo omo na, gegebi awon baba wa ti ma nse nitoripe oju kan ko le wo omo la.

## EJO AFOJUDI

O bere ninu iwe wa ose tokoja

Nigbati o di ojo keji ni ari Ogbeni Agusto ti o wa lati wa se fun Benson dipo Ogbeni Fani Kayode ati awon yio ku re.

Ogbeni Aguto yi fi han Adajo wipe, on kori ona ti won roju mo Benson ninu esun yi.

Oni ki Onidajo mase tele oro Ogbeni Adefarasin nitoripe eri o ri gbogbo oro awon sheri ko se dede pelu are won.

Agbejoro Ijoba fun ni esi gege bi o ti to ati bi o ti ye.
Ao da ejo na ni ojo kini osu lọsi yi.

Amu iwadi ejo na de opin ni ojo kerin din logbon osu yi.

# Awon Onisegun iko egbe Nilu Oyinbo



Awon ojogbon Onisegun so pe, arun iko egbe ko tun ni ewu gegebi o ti ri ni awon odun mewa sehin mo, pepelu awon ti arun buruku na npa nisisiyi, ko wopo to be mo, nitori awon Oyinbo ti kan egbogi re.

Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon omo ile Nigeria, ti nwon lo fi oju ri iru egbogi na ti o nse iwosan lona iyanu. Oruko won niwonyi - Lati owo otun, Ogbeni W. A. Usi, J. F. Awe, ati Iyafin Basuru.

## OMIRAN ALAKUKU ŞALAISI ẸLOMIRAN TUN GBODE

Alakuku ni omiran ti o ti wa nile Nigeria nigba ojo pipo, okiki re bere si kari aiye ni odun 1946 nigbati o nlo latikan si ekeji.
Awon enia so wipe, Omiran Alakuku ga to ese meje ati esun merin. Nigbati o nlo si Oke-Oya a gbo pe ko le duro ko le joko o dubule gbalaja ninu oko. O se iba ti o le se gegebi omiran sugbon nisisiyi, o ti ku a si ti gbagbe re.

(Wo yoku loju ewe keje)

E MA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

## Olorun Maje Ki Eleru Kuro Ni Di Eru Re.

O bere loju ewe kefa

Iwọ orẹ mi, duro ti af oriti ni igba iponju rẹ maje 'ro wipe ayipada rere ki yio ba o, tabi kio sọ ireti nu.

Ranti Bakanna pe ,Iyiowuawi ti Ọlọrun Ọba ni ase' Aba gbe enia pa si inu iho apata tabi inu ọgun' bi ati ko i w e akọle re be ni yio ri.

Nitorna roju f'ori ti isọrọ re, ayipada rere mbo wa.
Nigbati iyale iya re gbo wipe ọba pe, inu re baje, sugbon agbara re ko da ọmọ yi duro lati lọ si ọdọ ọba.

ỌMọ lọ da Ọba lohun, wọn mu bata jade lati fi diwọn ese re' ki ọmọ yi to ni ohun ,yio mu bata lati fi bọ ese r e, bata papa ti sare gere lọ wọ ese ọmọ yi.

Okiki ohun iyanu yi kan ni ilu ati l'oko, gbogbo enia si 'o wa lati wa wo ikan iyanu to sele.

Bayi ni ọmọ se di iyawo ọba.

(Ko yi ti Pari)

## KA LOSE TI MBO

Mo gbo tan, mo mọ tan ti ko je ki agbọn ni oro.
Ọrọ pọ nile.

## NI IRANTI

Baba Wa Ọwọn

DANIEL OKUNỌWỌ

Eniti o ku ti a sin ni

IJEBU-ODE

Lojo 28th Jan, 1920.
(Ogoji ọdun rekoja.)
Suare! Suare!! Suare!!!

OLOYE E. O. OKUNỌWỌ


CARSON PAINTS AND VANISHES



SOLE AGENTS :-

IKORODU TRADING COMPANY

20 & 28. Balogun Street Lagos.



FANTA Tonic

better than the best you've ever tasted!




MIXES WITH THE BEST

AUTHORISED BOTTLER

Nigerian Bottling Company Ltd.

P. O. Box 10, WHARF ROAD, APAPA.

TELEPHONE 55428


## Omiran Ala-kuku Salaisi Elomiran Tunde

(O bere loju ewe kẹfa)

Omiran ti o tun gbode nisisiyi ni ọkunrin kiribiti kan ti a npe ni akilapa Akilese ti ko ga ju ese marun lọ, sugbọn ti agbara pọ gegebi eranko gidigidi bi agbara re ti pọ to, bi o ba na apa re ti enia mefa, si joko le lori apa na yio duro sanṣan. Tabi kilo tun ku, bi o ba mu mọto kan dani mọta na ko ni lelo.

Lojo Sunday 31st ni yio tun fi gbogbo bi agbara re ti to han gbogbo awọn enia ni Empire Hotel, ni Idi Oro.


Mortgages 1st's & 2nd's also Re-Mortgages on all classes of properties.

Particulars :

E. N. FAMERICA LTD.

31 AVENUE MANSIONS,

LONDON N. W. 3.



LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"

# LAGOS RACE CLUB

## FEBRUARY MEETING 1960.

**SATURDAYS 6th, 13th, 20th & 27th FEBRUARY, 5th, 12th AND 19th MARCH, 1960.**

### FIRST DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Eight Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Five Furlongs Handicap Top "B" Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Eight Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5. 45 p.m. |
| RACE NO. 8 | Eight Furlongs Handicap Class "A" Division | 6.15p.m. |

### SECOND DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Six Furlongs Handicap Middle "B" Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Six Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3. 45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Seven Furlongs Handicap Top "B" Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Ten Furlongs Handicap Bottom Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Six Furlongs Handicap Middle "B" Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5. 45 p.m. |
| RACE NO. 8 | Six Furlongs Handicap Class "A" Division | 6. 15 p.m. |

### THIRD DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 pm |
| RACE NO. 2 | Five Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3.15 pm |
| RACE NO. 3 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Ten Furlongs Handicap Top "B" Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Five Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 5.15 pm. |
| RACE NO. 7 | Five Furlongs Handicap Middle "B" Division | 5.45 pm |
| RACE NO. 8 | Five Furlongs Handicap Class "A" Division | 6.15 pm. |

### FOURTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m |
| RACE NO. 2 | Seven Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3.15 p.m |
| RACE NO. 3 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3.45 p.m |
| RACE NO. 4 | THE JUBILEE CUP-Nine Furlongs Handicap-Top "B" Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Seven Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 45 pm |
| RACE NO. 6 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 5. 15 p.m |
| RACE NO. 7 | Seven Furlongs Handicap Middle "B" Division | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | Seven Furlongs Handicap, Class "A" Division | 6.15 p.m. |

### FIFTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m |
| RACE NO. 2 | Nine Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3.15p.m |
| RACE NO. 3 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Twelve Furlongs Handicap Top "B" Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Nine Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 45 p.m |
| RACE NO. 6 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 5. 15 p.m |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5. 45 p.m |
| RACE NO. 8 | Nine Furlongs Handicap Class "A" Division | 6 15 p.m |

### SIXTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Ten Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 45 p.m. |
| RACE NO. 4 | THE OMOLOLU CHALLENGE CUP Six Furlongs Handicap-Top "B" Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Ten Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 5. 15 p.m. |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5. 45 p.m. |
| RACE NO. 8 | Ten Furlongs Handicap Class "A" Division | 6. 15 p.m. |

### SEVENTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Maiden Four Furlongs Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE NO. 2 | Maiden Seven Furlongs Middle "B" Division | 3. 30 p.m. |
| RACE NO. 3 | Maiden Four Furlongs Bottom Division | 4. 00 p.m. |
| RACE NO. 4 | Maiden Eight Furlongs Top "B" Division | 4. 30 p.m. |
| RACE NO. 5 | Maiden Seven Furlongs Middle "B" Division | 5. 00 p.m. |
| RACE NO. 6 | POLO SCURRY | 5. 30 p.m |
| RACE NO. 7 | Maiden Seven Furlongs Class "A" Division | 6.00 p.m. |


**ARADAN NERVIGORA**

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agbara ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, allesun, ailokun ninu ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajdewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores** 12, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Oṣuṇpa) Ibadan.





Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O.B. Box 467 Lagos Phone 23370